# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL. XIV NO 94) LAGOS SATURDAY NOVEMBER 28 — DECEMBER 4 1964 KỌBỌ MEJI (2)


# Ijoba Yio Tu Ile Igbimo Apapo Ka Ni Oni

EKO — Irohin kan ta si wa leti fere wipe loni ọjọ Satide November 28, 1964, ni Ọ̣ọla alakoso Ijọba Apapọ Dr. Nnamdi Azikiwe yi o fi aṣẹ si wipe ki ile igbimọ apapọ tuka gẹgẹbi iwe akọsilẹ eto Iṣẹ apapọṣe Ijọba ilẹ Nigeria.

Ninu oṣu October 1959, ni a ti yan awọn aṣoju jakejado igun mẹrẹrin ilẹ Nigeria wa si Ijọba Ajumọṣepọ yi. Odun marun pere sini ofin sọ wipe ki igbimọ wa fun ki o to ni ayipada eniyan aṣoju miran.

Lati ọjọ Satide oni gbogbo awọn minisita ile wa yio pada lọ si ilu onikaluku lati lọ jiyin ohun rere ti o ṣe larin ọdun marun ti a fi yan si igbimọ.

Lẹhin eyi ni a o dibo lati yan awọn Aṣoju miiran lati ki a tun yan ẹniti o se tire bayege. Awọn ẹgbẹ oṣelu ti a npe ni N.N.A ati awọn kan ti a npe ni UPGA ti npolowo ibo lọ ka iri igun mẹrẹrin ilẹ wa lọwọlọwọ.

## Egbe Oselu Se Adehun Pelu Olopa

EKO — Ni ọjọ atalaia ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi ni awọn aṣiwaju ẹgbẹ oṣelu ti ilu Eko fi ohun ṣe ọkan pẹlu ara nwọn, Ẹgbẹ Alakuko, Ẹgbẹ Olomi, Ẹgbẹ Ọlọpẹ ati ẹgbẹ Ọlọwọ, wipe pẹlu iranlọwọ awọn ọlọpa awọn yio ṣe ipolowo ibo ti mbọ yi lai ṣẹ wipe ẹnikan di ẹnikan ni ọwọ.

Ipade na gba awọn n wa ati marun. Mallam Hamma Maiduguri ni o ṣe alaga ipade na ni inu ile ti a npe ni Lion Building ti ṣe ori fun iṣẹ awọn ọlọpa.

Oṣelu kọkan mu aṣoju meji wa. awọn ti o ṣe isọnigbe alaga ni igbakeji rẹ Ọgbẹni H.A.V. Ọmọọla ati Ọgbẹni J.E. Onubogu.

Awọn aṣoju ẹgbẹ Alakuko Ọlọpẹ, Ọlọwọ ati Ọlọ ọ ti mbẹ ni agbegbe Ikeja na wa pẹlu. Ọga awọn ọlọpa ni agbegbe Ikeja nawa Ọgbẹni S.A. Oshodi wa si ibẹ gẹgẹbi a woran.

Nwọn so adehun nwọn mọ ori nkan meje.

1) Nwọn ni awọn ko fẹ iwa janduku larin ilu Eko ati agbegbe rẹ.

2) Nwọn ni ki ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan ki o mayọ asiya ẹnikeji nitori ki alafia le wa ni ilu.

3) Ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan ko gbọdọ polowo ararẹ nibiti oṣelu keji ba nṣe ipade.

4) Gbogbo nwọn ti ara mọ lati kilọ fun ọmọ wẹrẹ nipa iwa janduku.

5) Nwọn gba lati gbe egun tabi abe jade wa si ibi ipade ṣugbọn awọn elegun tabi abe gbọdọ gbọran si awọn ọlọpa ni ẹnu.

(6) Awọn aṣiwaju ẹgbẹ oṣelu ni lati ran ọlọpa ni owo nipa fifi ọjọ ipade nwọn ranṣ si awọn ọlọpa ki nwọn si sọ ibi ipade na larin wakati mẹrinlelogun.

7) Gbogbo awọn oṣelu ti o wa ni ipade na fi ara mọ wipe awọn ọlọpa yio ma yẹ mato nwọn wo nitori ọn ọṣẹ ati ipalara.

Nwọn ṣe kilọkilọ fun awọn ọga oṣelu pe ki gbogbo nwọn lọ kilọ fun awọn ọmọ ẹhin nwọn lati ṣiwọ nibi mba ohun ini ọmọ ẹgbẹ keji ẹ, tabi wa ju oko fọ ile onile. Ki nwọn si tele aṣẹ ọlọpa lati dari si ibi ti ọlọpa ba dari nwọn si ki

**ẹniti awa moto nwọn mọ ofin daradara. Mallam Hamma ni ki ẹnikeni ti nwọn ba gbe iwa janduku wa ba ni ile tabi ni adugbo pe ọlọpa 999.**

## Emi Re Tabi Eru Re

EKO — Ni gbati oṣu ti o koja di mẹtal, Olosha kan wọle wa ba Ọl koni kan ti a npe ni Clement Oyebanji ni orere Igbosere ai ilu Eko ni ọganjọ oru.

Oyebanji fi ha adọ pe, ni ọganjọ oru on gbọ iro ẹsẹ enia ninu yara on, on bojuwọ on si ri ọkunrin kan gbagbara ti o yọ ọbẹ dani, o ni ẹru si ha on on fẹ kigbe.

Ọlọsha na si dahun pe ewo ni o wun ọ ṣe ni ninu mejeji, o ni a dakẹ ki on ko nkan ti on lẹ ko ni ibi ki o kigbe ki on nsi pa ọ. Oyebanji ni on ba kigbe Ole Ole Ọlọsha na bẹ ju si ita a ọ aladugbo sa mu.

Ni gbati a mu okunrin ọlọsha yi ti oruko rẹ njẹ Momo Sokoto de waju ọlọpa o ni on jẹbi.

**Pool ! Pool !!**
**Pool !!!**
**Wo awon Ayo Are Bolu Ose yi**

(Wo Oju Ewe Kefa)

ELETI – OFE
(A NJU WỌN KO ṢE WI LỊJỌ)
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" Lagos
P. O. Box 467, Phone 23370
VOL. XIV NO 849 SATURDAY Nov. 28 - Dec. 4 1964.

# Iwa Janduku Ko Tun Nkan Se

Orişirişi ipade ni a ri wipe awọn oşelu ti ṣe pẹlu ara nwọn ati awọn Ọga Ọlọpa nitori awọn ọmọ e ni jagidijagan ti awọn ẹgbe Oşelu nko kakiri, O fẹrẹ jẹ pe gbogbo ipade yi nj awọn oşe u na nfọkan awa mokunu na lẹ wipe nwọn yio da ọwọ janduku duro.

Gbogbo nkan ti a nfi oju rị nj ara ilu ko fi wa nj ọkan balẹ rara, ni lọlọ yi nj a gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ oşelu kan ni Ebute-Metta lọ ṣe ile ọmọ ẹgbẹ oşelu miran tị ko fi ara mọ ti nwọn.

Ọkunrin ko lẹ fi agbara fẹ obinrin, bakanna ni enia ko le mu enia ẹgbẹrẹ lati ṣe tirẹ pẹlu ipa tabi agbara, bi ko şe pe pẹlu ọrọ didun ati ododo ti mbẹ ninu rẹ.

A tun gbọ pe ni lọlọ yi awọn oşelu ilu Eko ti şe adehun ni arin ara nwọn pẹlu awọn ọlọpa lati ri ọwọ iwa janduku mọlẹ, ki igbesi aiafla le wa ninu ilu fun gbogbo wa

A bẹ ẹyin ti ẹ jẹ pataki pataki ninu ẹgbẹ oşelu lati ba wa şe iranlọwọ a ti ko iwa jagidijagan nwọnyi kuro larin ilu ati oko nitoripe eni lati ranti pe ti a ba di ibo tan yio ku wa ku ara wa.

# Awon Oselu Fi Owo Si Iwe

ABEOKUTA — Awọn aşelu ni ịlu Abẹokuta tị se eto tẹgẹ bi nwọn yio ti şe ma şe ipolowo ibo lai ni si ija rara, tabi jagidijagan.

Ninu ịgbade tị rwọn şe larịn nwọn pẹlu oga ọlọpa ọgbẹni G.B. Amu, awọn ẹgbẹ kọkau fi ara mọ latị şe ipade ipolowo ibo ni ịwọn ibusọ kan larin ara nwọn.

( Wo oju ewe karun )

# Iyawo Ri Siun Omi

LOKOJA– Iyawo titun kan ti a şẹşẹ gbe ni ịyawo fun ọkọ rẹ wọ ọkọ onigi ti oju omi lati Igua on lọ ba ọkọ rẹ ni ilu Ilokoja, ni a gbọ irohin pe o ri sinu odo şişan ti Benue pẹlu enia mẹta niran ti nwọn jẹ ẹbi ịyawo yi,

Nigbati irohin kan ọkọ rẹ enịti nse adajo ịbilẹ ni ilu Kwara, O da ọkan rẹ ru de po ti on na papa fẹ şe ara re ni eşe. Şugbọn awọn enia ti wọn wa ni agbegbe rẹ ti nwọn si mba ko ẹdun ko gba ni aye lati şe ara rẹ nị eşe.

Gẹgẹ bị irohin, enia mẹdọgbọn ri nbe ninu ọkọ igi na ki ọkọ na to da oju dele şugbọn mẹrin ninu nwọn ni o ku

EPELE O ! EPELE O !! EPELE O !!!

Ri iwọ ba nwa iwosan to daju, wa sile iwosan awọn :-

NIGERIAN ASSOCIATION OF MEDICAL HERBERLISTS

Nigerian Herbal Reaserch and Healing Centre
3, Willoughby Street, Lagos Branch.

O wa fun Ọkunrin ati Obinrin. Ẹrọ ni yio sọ ohun ti on şe Ọ Mo nfẹ alafia, Ẹmi gigun ati ọmọ rere laiye mi o, Dajudaju gbogbo wa mọ wipe ilera lọrọ aiye ? Ẹ wa si ile iwosan yi, pelu şile meta 3/–

Awọn Arun wọnyi :- Fun Obinrin :-

1 Ki oyun ọdun kan dabi oyun oşu mẹta.
2 Bi obinrin ba nri ẹjẹ ninu oyun loşoşu
3 Bi obinrin ko ba ri nkan oşu ti ko si loyun
4 Bi obinrin ba nla alakala
5 Ki inu obinrin tobi lasiko ti kosi ni oyun,
6 Ki abẹnu ma dun obinrin ni akoko oşu
7 Ki ẹda ma yọ obinrin lẹnu ati oyun iju toko jẹ
8 Ki nkan ma yika inu obinrin gbona, tabi ba oyun jẹ lara
9 Ki okan aya ma dun obinrin bi ẹjẹ ko ba to
10 Iwosan wa fun awọn arun afişe tabi kiko lara enia
11 Fun Ọkunrin :– Bi atọ şişan, ẹhin - didun jẹdijẹdi igbẹ ọrin, oyi oju.
12 Bi oko daku daji, atọ ti ko le dovun.
13 Kun inu, Kunsode, Ipake, ki ko arun lara obinrin, Ara-gbigbona ati ikọ orişirişi
14 An gba ẹbi fun awọn aboyun
15 Fun Ọmọde : - Giri, Okeile, Warapa, Jẹfun-jẹdọ, Ọlọ inu, Inu gbigbona
16 Ori pipariwo, Ara sisan
17 Asi nla oju ti ko riran.

Consult HEALTH OFFICER — Ojo iyewo — Ojojumo

3, WILLOUGHBY STREET, BY CORONA CINEMA, ALLI STREET, LAGOS.

Telephone :- 20286
Asiko Ise 7 a.m. to 10 p.m.

# Okunrin Kan Gbe Ori Obinrin Ti O Pe Ni Okobo

ABAOKUTA — Okunrin kan ọmọ ọdun mẹtalelogun ti o si ga ni iwọn ẹsẹ marun pẹlu ẹsun mẹrin, on ṣe iṣẹ ẹrọ lagilagi di ori m ndiya kan mọ i u pepa o si gbe wa si ọfisi awọn ọlọpa ni ilu Abẹokuta.

Nigbati ogbe de o tu o si gbe han awọn ọlọpa o ni eyi ni ori ọmọbinrin ti nję Loko Karimu. Emi ni mo ke ni ori nitoripe on pẹlu ọkunrin kan sọ kakiri wipe okobo ni on nṣe.

O ni onko ba pa ọ unrin na papa i o jẹ ọrẹ on ṣu gbọn on wa on ko si ri. Oni ọmọ obinri yi pẹlu ọrẹ on ni nwọn fa idi rẹ ti obinrin on fi kọ on silẹ lẹhin igba ti ọmọ rẹ ti o bi fun on ku, nitori ti awọn mejeji yi lọ sọ fun pe okobo ni on.

O sọ fun awọn ọlọpa pe ko si nkan ti o mu ọrẹ on polongo on kakiri pe okobo ni on ṣe bi ko ṣe wipe inu mbi nitori mo ni owo ati nkan iṣura julọ ni,

Oni on ronu pe ki on gbe ogun jẹ lẹhin igbati on ke ori ọmọ-obinrin na danu tan, ṣugbọn o sọ si on lọkan wipe ko dara bẹ, aiye gbọdọ mọ on ti o ṣe ti on fi pa.

Ọkunrin na wa ni ọdọ awọn ọlọpa lọwọlọwọ.

## Jaja Wachuku Nlo Si Ipade Agbarijo Orile-Ede

EKO — Ọlọ'a Jaja Wachuku yio ko awọn ọmọ ilẹ wa lọ ṣe ipade ti agbarijọ Orile-Ede ti a yio bẹrẹ ni ilu New York ni ọjọ kini oṣu kejila ọdun yi.

Awọn ti nwọn yio ba lọ ni Ọlọla Oloye S.O. Adebọ, eniti o jẹ aṣoju ilẹ wa ninu awọn ijoko agbarijọ Orile-Ede. Ọlọla Alhaji M. Muhammed Ngieruma, ẹniti ṣe aṣoju ilẹ wa innu ilu Larubawa ati awọn miran pẹlu,

Awọn Obinrin meji ti nwọn lọ ni Mrs. Adukẹ Moore (Amọ.Ofin) on na si ni adari eto iṣẹ awọn Mobil Oil ni ilẹ wa, ari Miss Margret Aguta (Amọ Ofin) ni ilu Port Harcourt.

Gbogbo nwọn yio fi ileyi sile ni ijọ kokandinlọgbọn oṣu ti a wa ninu rẹ yi, wọn yio wọ ọkọ ofurufu ni Ikeja ni agogo mejọ kọja iṣẹju mẹdoguu ni owurọ.

# E Dibo Fun Egbe Olowo

Eleyi ni Ikede fun gbogbo awọn ọmọ Igbomina Odo Ogun ati Ekiti fun ati dibo fun awọn Alabaṣe pọ wa N.N.D.P. fun ilu Eko Ibadan ati Ilifẹ o yẹ ki aduro ṣinṣin lori eto wa lati dibo fun awọn Nitori awọn ni won ni eto Eko ati ni gbogbo ilu ti o ku. Awa ti a kọ Iwe yi ati ri pe eo ṣe oju ṣeyin gẹgẹbi Ọmọ Igbomina A kesi gbogbo awọn Igbomina para ọkunrin ati lobirin, Iya Baba, ati Ọmọ lati dibo fun Ẹgbẹ Ọlọwọ awọn ni Alakoso wa.

Ikede yi wa lat

Ọwọ Abu Ọlọra.

N.P.C. Commette

Igbomina

Lagos Brance.

## Ki Olopa Se Iwadi Ni Ipa Gambo

KADUNA — Awọn obinrin ti ṣe ẹka egb NEPU ni ilẹ Ariwa ke si ọga awọn ọlọpa Ọgbẹni Louis Edet ti nṣe oga awọn ọlọpa ilẹ wa, wipe awọn fẹ ki oṣe iwad .Ba wo ni Alhaja Gambo oawaba ẹniti nṣe aṣiwaju awọn obinrin ẹgbẹ NEPU ni iha Ariwa ṣe ṣonu, ba wo ni nwọn ti ṣe ri pada.

Mallam Ladi Shehu ẹniti nṣe akọwe egba fun awọn obinrin NEPU ni iha Ariwa nsọ fun awọn o ni iwe irohin ni ilu Kaduna. O ni iwadi na jẹ ẹtọ ti awọn ọlọpa nilati ṣe.

Awọn oni iwe irohin bere lọwọ rẹ pe ki ni o ri ni ẹri ko fun awọn obirin ni ẹtọ nwọn ni ipinlẹ Ariwa

O ni o ya ọu lẹnu. Ni Ni iwọn igbati o ṣe pe nwọn ti ngba awọn obinrin ipinle yi si inu iṣẹ Ọlọpa, ko si nkanti ọgbọdọ di ijọba ipinlẹ yi duro mọ lati fun awọn obinrin to ku ipin awọn ninu ibo didi,

# Kotu Pase Fun Ogbeni John Lynn

EKO — Ni kotu giga ni ilu Eko ni ọjọ kẹtalelogun oṣu yi ni adajọ kotu giga pa l'aṣẹ wipe ki Ọgbẹni John Lyan

(Wo yoku loiu ewe kẹrin)

# Olosa Ni Agege

AGEGE — Awọn Ọlọsha bẹ ile Igbimọ ibilẹ ti ilu Agege wọ ni oru ọjọ Jimọ ti ṣe ogunjọ oṣu yi, nwọn si di ra wa pẹlu.

Wo yoku loju ewe karun )

# Olosa Wo Ewu Olopa

IFỌ- Awọn ọkunrin mẹfa kan ti oju nwọn le koko wa si ile ifi iwe ranṣe (GPO) ti o wa ni Ilu Ifọ ni ọjọ Alamisi ti nṣe ijọ konkọndinlogun oṣu yi. Meji ninu nwọn mura gẹgẹ bi Ọga ọlọpa Nigiriya;

Nigbati nwọn de ile iṣẹ yi nwọn fi ara wọn han ọga ile iṣẹ na ọgbẹni Wahabi Ajibade pe, awọn ni ọlọpa ọtẹlẹmuyẹ lati ilu Eko. Awọn gbọ ẹsun pe ọgbẹni Ajibade nrọ owo eru.

Nwọn ni ki o jọwọ ara rẹ ati gbogbo nkan ti mbẹ ninu ile iṣẹ na lati ṣe ayẹwo wọn kinikini Nwọn bẹrẹ si ṣe abẹwo yi de ibi ti nwọn fi kan ile ifi owo pamọsi,

Nwọn sọ fun pe ki o si ile owo na ki awọn wo inu rẹ pẹlu. Ọgbẹni Ajibade si si, Nwọn ko awọn owo bi ẹgbẹrun mẹta pọun ni owo gidi, Nwọn tun ko awọn ohun alumọni bi ẹlẹgbẹrun marun pọun pẹlu.

Nigbati nwọn ko awọn nkan wọnyi tan nwọn ni awọn mu ọgbẹni Ajibade ni orukọ ọba pẹlu aṣẹ ọba nwọn gbe ju si inu mato ti nwọn gbe wa, nwọn gbe lo si ọna Eko, Sugbọn nigbati nwọn de ibi kan nwọn ṣọ kalẹ, nwọn lu dadadara ki nwọn to julẹ.

Lọwọlọwọ yi a ko ti ri awọn ọlọsa na mu. Awọn ọlọpa ni ipinlẹ iwọ orun ti ti ẹsẹ bọ sokoto lati wa awọn ọlọsa na.

# Da[illegible]adana Merin Gba Ewon Odun Merindinlogorun

ONITSHA — Ni kotu gọran ni ilu Onitsha ni a gbọ wipe Ọlọla Onidajọ H.U. Kaine fi tẹduntẹdun da ẹjọ fun awọn Ọlọsha merin kan ti a fi ẹsun mẹfa kan ni iwaju rẹ.

Ẹsun ifi imọ ṣọkan, ẹsun fọlefọle ole jija ẹsun ibọn li lo, ẹsun ọta ibọn, ẹsun gareta fifi bo oju ati kiko awọn nkan ti a fi nfọ ile ti awọn ba fẹ jale.

Awọn mẹrin na ni Chukwueloka Aniowele, George Nwafor Nwankwo Ezema ati Charles Onu.

Awọn ọlọpa ni ọjọ kejidinlogun oṣu kẹsan ọdun yi awọn ọkunrin mẹrin yi ji awọn ẹru ti o le ni igba pọun.

Awọn ọlọpa ni awọn ri ibọn ti o ko ọta si ninu meji gba lọwọ wọn, nwọn si tun gba ọta ibọn mẹwa pẹlu rẹ nigbati nwọn ri wọn mu. Ninu idajọ rẹ Ọlọla Kaine ni on gbagbọ pe awọn ọdaran nwọ yi nlo ibọn wọn si nfi gareta bo oju wọn nigbati nwọn ba fẹ fọle tabi ṣọbu. O ni on ti fi oju wo wipe iṣẹ fifọle ati ole jija nṣ fẹ rin ilẹ ni ilẹ wa,

O ni ẹmi ati nkan ni wa ni ọwọ ewu nitori awọn ọlọsha nwọnyi.

O ni awọn Ọlọsa sọ Ominira wa ti a gba di ominira ile fifọ ati ole jija lati ma ko ile ipamọ, lati ma da awọn arinrin ajo l'ọna, nwọn si ṣe tan lati yin ibọn pa ẹnikẹni ti o ba di wọn lọwọ iṣẹ buburu yi,

O ni ki Chukwueloka ati Charles lo ṣe ẹwọn ọdun mejileladọta ẹnikọkan jẹ ọdun merindinlogbọn o ni ki George ṣe ẹwọn ọdun mọkolelogun ati Nwankwo pẹlu.

# Dokita Azikiwe Si Ile Iwosan Titun

EKO- Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe si Ile Iwosan ti awọn Oṣiṣẹ Ọkọ Oju Irin ṣẹṣẹ kọ si inu agbala nwọn ni Ebute-Metta. Pagidari ni ile iwosan na ti nwọn kọ ni pẹtẹsi alaja mẹtta.

Ọlọla Azikiwe sọ ninu ọrọ rẹ wipe, ọmọ enia ti o ie iṣẹ bọ lati igbati oju ti wa ni Orunkun lati ṣe wadi ọpọlọpọ nkan. nipa bi ao ti ma ṣe iwosan arun orisirisi ati bi a o ti ṣe gba ẹmi ọkan danu ki a si fi imọ dipo rẹ.

O ni ilosiwaju iṣẹ fi ara ti alafia ara awọn Oṣiṣẹ, O ni bi ẹṣiṣẹ ko ba ni ala ara ise ko le se, ti iṣẹ ko ba ṣe ilosiwaju ko le si ninu ilu,

O ni nwọn sọ fun on wipe alaga ti o ti wa ni bẹ ri Ọlọla Ralph Emerson ni olupilẹ ilẹ ile iwosan yi, Ṣugbọn nwọn ko kọ ni oju rẹ ki ko ṣe igbati Dokita Okechukwu Ikejiani gba ipo rẹ ni ile iwosan na bọ si kikọ. Odupe fun awọn mejeji ati iṣẹ nwọn ti wọn ṣe.

# Kotu Pase

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

ti nṣe ọga ọlọpa inu ilu Eko fi owo tabi nkan ini rẹ ti o to ẹgbẹrun meji pọun lati san si ọdọ akọwe agba kotu, ki ẹniti o ba duro fun Lynn papa san iye owo kanna gẹgẹbi iduro nitori ẹjọ ti a pe.

Onidajọ ni ki ẹniti o pe ni ẹjọ papa san apo mẹrin si ọdọ akọwe kotu gẹgẹbi idurc tirẹ na.

Ọgbẹni Anthony Golden Okoctha ẹniti o nkọ iṣẹ amofin ni ilu Oyinbo ni o ti onwa lati pe Ọgbẹni John Lynn ni ẹjọ, o si ni on yio gba ẹgbẹrun pọun ọna ọgbọn ni ọwọ rẹ ti on ba jaye rẹ.

# Awon Oselu

O bẹrẹ Lẹju ewe keji

Nwọn si tun fi ara mọ wipe awọn ko gbodo ṣe ipade ipolowo ibo ni iwaju ile isiju ẹgbẹ oselu tabi ni ile iṣẹ nwọn tabi ni ile itaja nwọn.

Nwọn sọ wipe ẹgbẹ oselu kan kọ gbọdọ lọ si ipade awọn ẹgbẹ oselu miran; tabi ki nwọn kọ orin owe, bẹni a ko si gbọdọ ho b... n.

Ọga awọn ọlọpa ti ha pe o i wa ninu ofin eto mato pe ẹnikẹni ko gbọdọ rọ mọ mato ... i ẹhin. Nitorina ki a kilọ fun awọn ọmọ wa ti ma rọ mọ mato ipolowo ibo ni ẹhin.

## Arikogbon Owe Oyinbo Ni Ede Yoruba

(1) Enia ko le ri nkan rere gba lai ṣe iṣẹ rẹ.
(2) Ẹda ti o ba tan imọlẹ fun ẹda igbe rẹ ko le ti inu rẹ kuro.
(3) Idakẹ ịẹ dabi wura sugbọn ẹbi ni on ja si
(4) Ọpọlọpọ ẹtu ni ki nṣe efi ti o si ni ewu fun ẹda.
(5) Ireti a ti ni on ti a ko ti ni, o nko wahala ba ẹmi.
(6) Ọrọ ti o ju lọ fun ọkunrin ni alafia ati iyawo daradara.
(7) Omi a ma yo ni ti aba fi ẹsọ mu.
(8) Nkan ti a o ṣe ti yio bajẹ loni, fi ti di ọla.
(9) Imọ ki nṣe agbara, ṣugbọn ogun agbara ni.
(10) Ẹni ti o ba sọ gbogbo on ti o bi mọ tan yio sọ on ti ko mọ si.
(11) Ẹkun korikoto ko le ni ki ọka ma pọn.
(12) O Dara ... i a ran ẹnikeji lọwọ ki o bọ si fun gẹgẹ bi ti wa.

...awọn ile iṣẹ ọkọ ojurin ti a ṣẹṣẹ ṣe lọ si ilẹ Bornu.

Nigbati o ba ... yio mu d... ni de ninu awọn adari eto iṣẹ ijọba rẹ dani wa, nwọn yio si pade rẹ ni Maiduguri Ọgbẹni Haman D... ko ti ṣe aṣoju ilẹ na ni ilẹ wa nihin pẹlu awọn ti yio pade rẹ.

A gbọ wipe awọn ijọba Cameroun nṣe imura lati ṣe oju ọna ọkọ ojurin wa si ilu ti a npe ni Chad, ko jina si ilu Bornu Boya ilẹ wa na le fa ti nwọn l...ti Bornu de Chad. Eyi fi han wipe ilẹ awa enia alawọ dudu nṣe fa sun mọ ara wọn.

## Olosha Ni Agege

AGEGE - Awọn ọlọsha b... ile igbimọ ibilẹ ti ilu Agege wọ ni oru ọjọ Jimọ ti nṣe ogunjọ oṣu yi, nwọn si di ... wa pẹlu.

Ogbeni Jọnu Alabi ẹniti nṣọ ile igbimọ ni Agege fi ye wa pe, ni iwọn agogo meji ọganjọ oru, awọn kan gbe moto wa si ile igbimọ na nigbati nwọn sọkalẹ ni nu moto on ri awọn enia gbagbara merin ti nwọn bọlẹ lati inu moto na.

Nigbati wọn sọkalẹ wọn kori si ọna ọdọ on, ṣugbọn ki on to bere pe ẹyin ta ni, nwọn ti ki on wọn si wọ on lẹ si ibi ile owo, nibẹ ni on ri awọn aṣode miran ti awọn ọlọsha nfi ibọn sọ.

Ogbeni Alabi ni nwọn ko awọn ti mọ inu ile iṣẹ kan nibẹ, nwọn si fi agbara ṣi ilẹkun wọ inu ofisi, nwọn gbe agogo ara ogiri kan ati ẹrọ itẹwe kan ti a npe ni Olympia.

# Ahidjo Yio Wa Ile Wa

CAMROUN - Baba ẹgbẹ ilẹ Cameroun Ogbẹni M. Ahmadu Ahidjo, ti fi ara mọ iwe ipe kan ti Baba ẹgbẹ ilẹ Nihin Ọlọla Dokita Azikiwe fi pe, wipe on fẹ kio bẹ ilẹ Nijiriya wo ni asiko ti on ba si

# Ewon Odun Meji Fun Egungun Enia

KADUNA — Ni kotu Alikali ni ilu Kaduna ni awọn ọlọpa fa apo iwe kan jade ti a ri egungun enia ninu rẹ.

Ọkunrin ti a npe ni Sunday York ni awọn ọlọpa mu esun rẹ wa sọ fun ọlọpa pe obinrin kan ti o nje Grace Ugochukwu ẹ i ti on pẹlu Sunday njọ gbe ile kan nta igbo.

Awọn ọlọpa ni nigbati o to ọjọ kẹta Sunday wa fi ẹjọ sun pe obinrin na tun ni egungun enia lọwọ rẹ. ṣugbọn nigbati awọn ọlọpa lọ ṣe abẹwo ile obinrin yi a ko ri igbo tabi egungun enia ninu ile rẹ.

Sunday ni egungun enia na wa ni enia ile idana awọn. Nigbati nwọn de ibẹ wọn ri, ṣugbọn nigbati awọn ọlọpa wa idi rẹ daradara a ri wipe Sunday York ni o ni egungun enia nwọnyi, o fẹ lati ko ba Grace ni.

O sọ fun adajọ pe on jẹbi ki nwọn wo ṣe fun on. Onidajọ ni iwa iwọ Sunday York buru pupọ nitorina ki o lọ ẹwọn ọdun meji.

# Fani Kayode Je Balogun

ILE-IFE Ilu Ifẹ kun fun arinrin ni ọjọ Satide ti ṣe ọjọ kokọn'elogun oṣu yi; Nigba ti ọba Aderẹmi ti nse Oni ile Ifẹ fi awọn meji ninu awọn ọmọ ilu na jẹ oye meji pataki.



OLOYE FANIKAYODE

Ọba Oni fi oloye Remi Fani-Kayode ti ṣe igbakeji Olotu ipinlẹ Iwọ orun jẹ Oye Balogun ti ilu Ife, o si tun fi Adehunse James Omitowoju, ti ṣe Oludari eto lera ni ipinlẹ iwọ Orun jẹ oye Woye ileri ti Ife bakanna.

Olotu ijọba Iwọ orun oloye Akintọla pẹlu ọpọlọpọ ninu awọn oludari eto iṣẹ ijọba kun fun ayọ oti oyinbo si nlo bi rẹrẹ lati fi yọ fun awọn oloye meji na.

# Awọn Danadana De Ikeja

IKEJA — Awọn Danadana bi mẹfa ni nwọn ki mọto agbaowokọ ti awọn oṣiṣẹ ọkọ ofurufu mọlẹ pẹlu agbara nwọn si ko owo ti o wa ni inu mọto na. Owo na jẹ ẹgbẹrun pọun pọnọ mẹrinlelọgbọn ti o lọ gba ni ile owo ti o wa ni iwọn igba ẹsẹ si ibi iṣẹ wọn.

Alafojuri kan sọ fun wa pe awọn Ọlọsha yi gbe ibọn si Ọgbẹni Lewis Enemokwu lati pa ki awọn ọlọsha yi to le ri owo na gba nipa fi fi agbara si ibi ti Enemokwu gbe owo na si.

Ọgbẹni Bower ti on pẹlu Enemokwu jọ lọ si ile owo sọ wipe on ri mato Opel Rekord kan ti o tẹle awọn nigbati awọn nlọ. Nigbati a de ile owo ti on bọ si ilẹ on ko ri mọto na mọ.

Awọn wọ inu ile owo awọn si gba owo ti awọn fẹ gba, awọn gbe owo na si ẹhin mato, nigbati awọn de ile iṣẹ awọn, on tun ri mato Opel ti o tẹle awọn nigbati awọn nlọ ile owo o tun ba awọn wọ ile iṣẹ awọn.

Awọn ọlọpa ti so ọna kakiri lati se abẹwo gbogbo awọn mato ati awọn ero ati ẹru ti nwọn ko kọja. A gbọ wipe awọn ri ọkunrin kan ti nka ọpọlọpọ owo pepa ni ọna Ikorodu, Boya ninu owo ti nwọn ṣẹṣẹ ji yi ni tabi imiran awọn Ọlọpa koi ti le sọ bi awọn owo na ba wa ninu owo ti nwọn ṣẹṣẹ ji yi.

# Onigbese Be Olowo Lori Ni Ugheli

UGHELI — Ọgbẹni Boyi Atunisha ti mgba ekurọ lọ sin owo sile mẹwa ti a ti jẹ fun iwọn oṣu mẹfa ni dede agogo mẹwa owurọ.

Ṣugbọn nigbati o de ile Onigbese rẹ, Onigbese na bẹbẹ pe on ko ti ni owo na loni, on yio fun ni ijọ marun.

Esi yi ko tẹ Boyi lọrun o ni on yio gba owo on ni eni yi ni, nwọn bẹrẹ si ta ohun si ara nwọn ni o ba di ija larin awọn mejeji.

Ija na gbona gidigidi, Onigbese fa ada yọ o ke Boyi ni ori.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370.

OLOTU ) B. A. CAREW 43. Offin Road, Lagos.

# Omo Olomo Ko Se Gba So Mo

Ọba da a pa enia yi duro fun igba die, on ati awọn ojoye rẹ si wọ inu afin lati ṣe aṣaro. Nigbati nwọn de bẹ onikaluku yẹ ọrọ na wo, nwọn si wo itumọ oṣu orire, awọn oloye ni gẹgẹ adehun o jẹbi iku, Nitorina awọn fi ara mọ ki nwọn bẹ ni ori.

Ṣugbọn arugbo kan ninu awọn oloye je a moye, o sọ ni gbolohun kan ba yi pe, eyin enia mi dajudaju on gba wipe oloye jebi Adehun, ṣugbọn ewo ni irẹ ninu oṣu rẹ na.

Dajudaju, ni pa fi fi inu han iyawo rẹ ni ọba ṣe mọ itumọ awọn oṣu mẹta nwọnyi. Ni ododo obinrin ko se fi inu han.

Arugbo oloye na tun fi han nwọn wipe, ọmọ ọlọmọ ko ṣe gba se ọmọ, bẹ ni ni ododo, ko ba ṣe wipe on ni o bi ọmọkunrin ti o wa ro ẹjọ aṣọ fun ọba ko ni rojọ aṣọ bi ko se wipe yio bẹbẹ fun dida ẹmi baba rẹ silẹ.

Ọba ni ki nwọn de obinrin na ki a si bẹ ni ori danu. eyi ni ẹsan fun obinrin ti o ba fẹran owo ju ọkọ rẹ lọ, otitọ mo ṣe adehun wipe no da ile ati ọna si meji fun ọ, loni yi ọrọ na ko ri bẹ mọ. nitori on ti o ṣe ojoye mi lati ọwọ Obinrin le pada wa ṣe emi na, ki eleyi jẹ ẹkọ fun gbogbo Obinrin ilu pe a ki fi aṣiri ọkọ ẹni han.

Ni ori ẹkẹta Orun san iku Kabiyesi Ọba ẹ wo ẹniti a fẹ pa, o si sun lọ fọn fọn. Ewo ni o jẹ irọ ninu awọn oṣu mẹta yi. O ni on bẹ Ọba ki o da si nitoripe awọn oṣu na kọ ni ni ọgbọn nwọn oloye si dọbalẹ pẹlu rẹ lati bẹ ọba, ọba si gbọ ẹbẹ nwọn o da oloye na silẹ.

Ọba ni ki nwọn mu ọmọde kunrin ti o rojọ aṣọ kuro ninu ilu yi ati agbegbe ilu na. O ni ti o ba ṣe wipe baba rẹ ni adanwo nla iru eyi bọiu nje ki yio ma ralẹ ni iwaju ọba fun idariji Nitorina otito ni ọmọ ọlọmọ ko se gba ṣeọmọ.

Ọba ni ida on ki yio ja de ki o si wọle lai ko mu ẹjẹ. Nigbati nwọn bọ ni gbangban, ọba ni ki nwọn tu oloye na silẹ on fun ni idariji nitoripe ko si irọ ninu awọn oṣu rẹ mẹtẹta, O ni ki nwọn mu iyawo oloye na jade si gbangba, ọba o han ara ilu pe obinrin yi ni on bẹ ni owẹ lati ri aṣiri ọkọ rẹ. Nitori na on gba wipe obinrin ko ṣe fi inu han.

Oloye na pade wa si ile rẹ pẹlu are ati ayọ gbogbo awọn ojoye yoku ba de ile rẹ. O da nwọn duro, o se ase fun nwọn, o fun nwọn ni ọti ati owo.

Ba yi ni itan yi pari si. eyin ọkawe wa ẹfi oju inu wo ọrọ na, gẹgẹ bi o ti se bẹrẹ ati ipari rẹ dajudaju oye ati ọgbọn mbẹ ninu itan na. O di ọsẹ ti nbọ ki a to fun yi ni imiran.

## Awon marun to daju

**Wolves–Shefield ; Maucity–Bolton**
**Darlington–Lincoln. T. Lanark-Celtic.**
**Charlton–Plymonth**

**Perm meta ninu marun–Line mewa.**